ADURA FUN OSE YI

Lowo ota ile ati tode Oluwa rere gba wa.

# IRAWO ★ OBOKUN

OWE OSE YI

Gele ko dun ti ba mo we.

Vol 3 No. 135 ILESHA. MONDAY, APRIL 25 1955. IYE OWO: TORO

# OLOLA ROTIMI WILLIAMS SI IPADE IJOBA TITUN TI ILE IJESA



QLQLA J. O. FADAHUNSI

On na wa pelu ogunlogo awọn oselu ti o rọ si ipade kini ti Ijọba titun si ase ni ọjọ kọkandinlogun osu yi. On si ni ẹniti afi ibo yan lati ma se alaga ipade na.

## AWỌN KANSẸLỌ N C N C ṢE IPADE

Lati nkan bi ọsẹ meji sẹhin nigbati idibo ti pari ni gbogbo awọn Kanselọ to wọle loruko N CNC ti nmura lati se isin idupẹ ati ipade.

Gbogbo ile ijọsin Ọlọrun ni wọn rause si lati gbadura fun wọn fun iranlọwọ ati atilẹhin Olọrun nipa ifidimulẹ ijọba ti un awọn gbe le wọn lọwọ.

Ni ọjọ karundinlogun osu yi ni gbogbo awọn Musulumi se adura fun wọn.

Ni ọjọ kẹrindinlogun osu yi ni awọn ọjọgbọn enia ama mọ ijọba ba wọn soro. Ẹniti o kọ soro ni Ogbẹni H. S. A. Adedeji B. com (Leed) o ba wọn soro lori ofin Ijọba akamọ ati igbekalẹ re. Ibi ti o ti wọro lowo ni Ogbẹni C. A. Balogun fi ari o orin to afi eto olugbohun ko ninu mọlọ awọn Action Group se idiwọ fun awọn to ngbọ ọrọ re. O ni lati da ero duro ti ti Balogun ati awọn iso- be re fi kigbe koja.

Ẹniti o soro lehin ti Ogbẹni Tunji Olowofoyeku, B. A., L. L. B. On na ba wọn soro lori eto Ijọ-pade. Ẹnikeji to ba wọn soro ni Ọlọla J. O. Fadahunsi o ba wọn soro lori ise Kanselọ.

Ọlọla Olu Komolafẹ na fi anfani na lọwọ lati ba wọn soro lori Relewe Akintola.

Awọn Kanselọ to wa nibẹ ju ọrundinnirinwo, bosi awọn Ijoye to wa nibẹ ju igba lọ.

Ọpọlọpọ awọn Oloye ati awọn Kanselọ to fi ara mọ Action Group lo wa nibe pelu. Inu gbogbo wọn lo dun fun anfani ribiribi ti NCNC fun wọn lati ni imọ nipa ise ala ti ilu gbe le wọn lọwọ.

Lehin igbati wọn soro tan ni wọn fi burẹdi pelu bota panu ti wọn si fi oti tọ.

Ni ọjọ kẹrindinlogun osu yi ni wọn lo si ile ijọsin ti Ilọrọ ti wọn ti se isin nibẹ.

Alufa D. O. Yoloye to se isin na fi ọpọlọpọ ọrọ gba wọn ni iyanju, fi ye wọn pe ti wọn ba ti le ni igbagbọ ati igbekẹle si Olọrun, bi awọn ọta ti le mas lati ba ise le mọ wọn lowọ dade ni yio ma yori si.

Ogunlogo awọn enia pataki pataki lo lọ wa nibi isin na.

Komolafe Onisowa koko lati ... Ogbeni J. A. Famodun, E. O. Famakinwa, L. O. Orimagbe, J. A. Ola, S. A. Idowu. Lati College ti Aposteli Oke-oye Ilesa.

Omidan J. O. Oke, I. O. Olokorun, Arenso.



QGBENI J. ADEDEJI

On ni alaga awọn ẹgbẹ Afenifere A.G ti ilu Iwara, on na je ọkan ninu awọn asoju fun ilu na.

On na pelu Ogunlogo awọn asoju ti 'owa si Obokun ẹbusi ni ọjọ ti afi eto Ijọba titun lele.

## QMQ LO'KU Ẹ MA KU AṢẸHINDE

(Lati Qwọ J. O. Faloye Iwarẹ)

Ni dede agogo meji ọsan ọjọ alamisi 7/4/55 ni ile iwe Aposteli Ẹsa-Odo kun fun ọpọlọpọ enia Ogbẹni Joseph Ọmọyẹmiwo-Faloye fi jijẹ ati mimu te awọn enia wọnyi lọrun.

Ogbẹni S. O. Ademakinwa, ọga ile iwe Aposteli ni ojoko lori aga. Ogbẹni A. A. Ademiju sa gbogbo ipa re lati ri wipe wọn se eto onje wọnyi ni akoko ati pe wọn si pin fun olukuluku lasiadogba.

Ogbẹni A. O. Adeniyi sọrọ pupọ lori Ogbẹni Faloyẹ (ọmọ loku) & (the Host) o fi ọdun ba itan igbesi aiyẹ ati iwa rẹ. Ogbẹni Faloye si dupẹ lọwọ alaga ati gbogbo awọn ti o wa, fun ifẹ ti wọn fi han nipa wiwa wọn, o si tun dupẹ bakanna lọwọ Ogbẹni Ademiju fun awọn ọrọ ti o so nipa on.

Lehin eyi ni gbogbo ile wọdi kẹ te lo si gbangba ria agbebe lati ma gbadun ara wọn pelu ilu ati ijo. O to asan bi agogo mọkanla oru ki ato kuro ni ibi ijo na. Die nínu awọn ti o wa ni wọnyi: Ogbẹni S. O. Ademakinwa ọga ile iwe Aposteli Ẹsa-Odo S. O. Oladele ọga ile iwe United Shchool Ẹsa Odo. Awọn Oluko lati Apostolic School A. A. Ademiju S. O. Lowojori, E. O. Aregbesola E. F. Ogunlumroti, E. O. Komolafe, J. O. Ajojo.

Awọn Oluko lati United School Ẹsa Odo ni awọn Ogbẹni A. O. Adeniyi, Osunniyi, Falana, Omidan B. M. Adetanji & B. A. Ajayi Ogbẹni I. O. Famakinwa Oluko lati C. M. S. School Iwoye I. O.

## ENIA MERIILELENIGBA PELU KANSELO MARUN FI EGBE NCNC SILE NI AMUYE

Ni ojo Monday Eyi ti ese ojo okanlelogun osu March (21/3/55) ni awon merin-elugba (204) ninu awọn ọmọ Ẹgbẹ NCNC (Ẹgbẹ Akukọ) Ati Alaga wọn Ogbẹni A. D. Ogbara fi Ẹgbẹ N C N C silẹ ti wọn si di ọmọ Ẹgbẹ Action Group (Ọpẹ) Afẹnifẹre.

Idi re ti awọn fi kuro ninu Ẹgbẹ Akukọ ni wipe Ẹgbẹ na ko ti le fẹran ara wọn denu atipe awọn fẹran ati ma fi ileto kan ti o ba tobi si abe eyi ti o kere. Pari pari rẹ ni iro ala ala ti awọn ma npa, Kakiri lai ronu igbati iro na yio ba jadi. Ara iro na sini Iru ile iwe ọfẹ ti awọn ni koni si ti o ti wa wa lode oni yio.

Kundekunde Ẹgbẹ na si mule bakanna wipe awọn yio tan sile meje abọ (7/6d) fun awọn onise fun owo ojumọ eyi ti awọn pe si sile meji ati tọrọ lehin ti awọn dibo fun wọn tan. Bẹni Ọlọla Awolowo ko da sile marun 5/ tire duro rara.

Bayi Bayi ni ki ama rio. Ẹyin ọmọ Obokun nde ati ni Agbegbe Ẹpoda lehin itanje Awọn Alakuko o.

Owe Yoruba kan fiyewa wipe koni nkan ti ọmọ Ẹye yio ṣe fun iya re abo ba bagba ko fo sinu igbe ki owe na je ti awọn Agba o.



QMQ OBA F. LADEJOLA QGINI

On je enkan pataki ninu awọn Ijesa ti owa ni Eko, on awa igbega ati itesiwaju ilu wa nigbagbogbo ti aba pe fun iranlọwọ.

## JIJE OYE ARAPATẸ
(Lati Ọwọ Idile Arapata)

Eyi ni iwe ẹbẹ ti awọn idile to lẹtọ nipa jijẹ oye Arapatẹ kọ si Ijọba ibilẹ Ijẹsa, Ajẹle ti ilẹ Ijesha Minista fun iṣeto ijẹba ibilẹ Residenti t Ọyọ ati Irawọ Obokun Lati ọjọ kewa oṣu yi ni iwe na ti te ni iọwọ, ṣugbọn o dun ni pe a ko ete raye gbe jade, iwe na kọ bayi

A gbọ pe Ọlọla Residenti ti Ẹkun Ọyọ bẹ Ilesa wo laipẹ o si si ẹniti a yan lati di aye oye Arapate to si sile. Lẹhin igbati Residenti na lọ tan a tun gbọ agbẹrọ pe awọn kan ninu awọn oloye Ilesa ti fọwọ si iwe fun Abudu Sarumi pe on ni awọn fẹ ki o joye na

Adura wa nipe ki agbọsọ na maṣe jẹ otitọ ṣugbọn to ba jẹ otitọ awa idile to lẹtọ jijẹ oye na mbẹ ẹnyin ajuọlọ lati ripe a dabo bo ẹtọ wa lati yan ẹniti yio jẹ olori na

A mọ pe wọn ṣe ofin ifinijoye kan laipẹ. Agbọ pe ofin na fun awọn ijoye lagbara lati ma fọwọ si iwe ẹniti o yẹ kio joye, ṣugbọn a tun mọ pe ofin na tọka pe ẹni iti idile ba yan ni ki awọn oloye ma fọwọ si.

Ti eyi bajẹ otitọ a ripe awọ oloye na ti lodi si ohun ofin tọka nipe fi fọwọ si iwe fun Ọgbẹni Abudu Sarumi. Nitoribẹ a bẹbẹ pe ki ẹnyin ajuọlọ maṣe gba ifọwọsi na.

Gẹgẹ bi gbogbo awọn oloye Ilesa ti mọ, idile mẹta lo lẹtọ lati yanni joye Arapatẹ. Lati ripe kosi ikunsinu ti o ma nkẹhin ariyanjiyan ti didu oye ma nfa, ati lati ripe irẹpọ ati ifẹran larin awọn idile wa, a pinu lati ma gori oye na ni tẹlẹntẹlẹ.

Nitorina lẹhin ọpọlọpọ ipade fi idibo yan idile Sagilakkọ, (Fadugba) lati yan ni joye na. N ọjọ kẹfa oṣu June ọdun 1944 ni a se ipade na idile na yan Ọgbẹni A. O Fadugba. Lẹhin igbati wọn fi han wa, ti a si gba, awa na fi han awọn oloye Ilesa gẹgẹ bi eto ati aṣa

Ṣugbọn ohun to wa ya wa lẹnu nipe lẹhin igbana, awọn oloye kan wa nghe sẹhin Abudu Sarumi ẹniti o wa lati idile Lọraye, ọyọ idile kanṣoṣo na ti ko fọwọsowọ pọ pẹlu awọn idile arapatẹ yoku

Ẹnyin alagba, ifẹ wa ni lati ri irẹpọ ninu awọn idile wa, a si ri mọ pe ọna to ti le ṣe e se nipe ki a ma fun olukuluku idile ni ẹtọ lati joye Arapatẹ ni asiko to ba kan wọn; nisisiyi o ti yikan idile Sagilakọkọ nitoripe ẹnikẹni ko i ti jẹ ni idile na lati igbati ogun enia dudu ti pari

A gba wipe nipa fifọwọ si iwe ẹni odi lati ṣe olori idile wa dabi ẹnipe awọn ijoye to fọwọ si na fẹ da ifẹhinkẹhin sarin idile wa

Awọn oloye ni olori idile wọn, ẹnikẹni ti o ba si joye Arapatẹ ni olori idile Arapatẹ. Nitorina a fi tọwọtọwọ bẹ ẹnyin ajuọlọ lati ba ni bẹ awọn oloye na pe ki wọn ran wa lọwọ lati ripe irẹpọ ati fifi ifẹ fọwọsowọ pọ ṣe nkan wa larin idile wa gẹgẹ bi awọn na yio ti fẹ pe ki o wa larin idile ti wọn

Ki a to pari iwe ẹbẹ wa, a fi anfani yi kẹwọ lati sọ pe a wa ni itẹriba si Ọba Ọwa ti ilẹ Ijẹṣa ati alagbara julọ Ọbabirin ti ilu Gẹsi.

AKỌLE OLOTU:- Awọn to fọwọ si iwe ẹbẹ na ni Lodahun Agboluaje, lati idile Lọdahun; A. O. Fasimirin, lati idile Sagifakọkọ; Aluko Ajiyọ, lati idile Ajiyọ ati Jacob Jẹgẹdẹ, lati idile Agbangba Awọ



OLOGBE ALUKO MAKINWA.

o ni ẹniti gbogbo enia ma npe ni Aluko Iwara o si jẹ ẹnikan atakiṣninu idile Makinwa, awọn ọmọ rẹ pẹlu si ṣe inawo nibi ariya Ologbe J. M. Makinwa.



ỌGBẸNI J. O OGUNṢEITAN

On ni Baba Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni Ilẹ Ijẹṣa on na si wa pẹlu ognnlọgọ awọn ọmọ ẹgbẹ yi ti o lọ si ibi ipade kini ti aṣe labẹ eto Ijọba titun.



## IWE ALAGBAFO ASO

A ṢE IWE YI FUN ANFANI AWỌN ALAGBAFỌ ATI AWỌN

A NFỌ AṢỌ FUN. NIPA IWE YI AṢỌ KO SỌNU MỌ, RARA ARIYANJIYAN KO SI MỌ NIPA AṢỌ.

TETE RA TIRẸ KI O TO TAN. IBA DIẸ NI A ṢE.

O RI IWE YI RA NI OFFICE:- IJESHA PRESS LTD.


## AKIYESI

FUN GBOGBO OMỌ ẸGBẸ ACTION GROUP ỌPẸ

A fẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ Action Group mọ pe ipade ọjọ-mẹjọ-mẹjọ ti a nṣe ni Wednesday ko yi pada nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sọkan lati ma wa si gbogbo ipade dede.

AKỌWE

## AKIYESI PATAKI

Ki ẹnikẹni ti o ba fẹ kowe sinu iwe Irawọ Obokun ma kọ orukọ ti on papa njẹ pẹlu adugbo rẹ. Toripe ọpọ iwe ni anri gba laisi orukọ. Eyiti ko basi ni orukọ ko ni tẹ jade.

ALABOJUTO



OGBENI E. FADAHUNSI

On je ẹkan ninu awọn enisowo petaki ni ilu Ilesa, on na si wa pẹ lu ogunlọgọ awọn ti o lọ si Obokungbusi lati lọ wo Igbekalẹ eto Ijọba titun.


**Bring your Printing Jobs to:-**
Ijesha Press Ltd.
Okesha Street,
ILESHA.


## AKIYESI

A fi eyi kede fun gbogbo awọn aṣoju wa ti mba wa ta iwe ti ohin yi pe, aṣoju k'aṣoju ti ko ba san owo iwe tire ki o to di ipari Ọsẹ kini ti yio tẹle Oṣu, a o da iwe rẹ duro lai si ifilọ tabi ifisun.

Nipa aṣẹ
A aboiuto

## IYỌRISI IBO IGBIMỌ MUROKO ATI TI AWỌN IJOYE AGBECBE ILES A

Ni ọjọ kejila oṣu kẹrin ọdun 1955, ni'lu Ilaa ti Ijẹṣa, Igbimọ Muroko fi idibo yan Oloye S. Adeyẹy Ata-iyerọ, Ararọmi ti Iṣireyun si ipo Alaga igbimọ na lori eto ijọba titud laisi alatako.

Ni ọjọ karun oṣu kẹrin 19-55, ni agbọ pe gbogbo awọn Oloye agbegbe Ilesha dibo yan aṣoju meji. Lọja Isire-yun, Oloye Ṣ. Adeyẹye Ta-yierọ lo moke ju ninu ibo na. O gba ibo mẹrindilogbọn Oloye Aloko ti Iloko gba mẹrinlelogun (24). Oloye Awara gba ogun (20) Lọja Oṣu si gba ibo marun (5)

Bayi ni ibo mu oloye S. Adeyẹye Ataiyerọ Ararọmi Iṣireyun, ati Oloye Aloko ti Iloko lati ṣe oju awọn Ijoye agb gbe Ilesha ninu ipade gbogbo gbo ti Ijẹṣa. Awọn mejeji bẹrẹ iṣẹ aṣoju na ni ọjọ kọkandinlogun oṣu kẹrin 1955, ọjọ ti a si ipade Ijọba titun l'ori'le Ijesha.

## WỌN EBI OLOCBE J. M. MAKINWA SE ARIYA

Lati ọwọ J O Awosan.

Lati ọjọ saturday titi ọjọ kẹsan osu yi, niawọn aburo ọmọ, ebi ati awọn ojulumọ ologbe ọgbẹni J.M. Makinwa ti ose alaisi laipẹ yi ti nse imurasilẹ fun ati se ariya oku na ogunlọgọ awọn alejo lati wa lati awọn ilu bi Eko, Ibadan, Ifẹ, Akure, Ilorin, ati ọpọ ilu fun ti ariya na.

Gbogbo awọn idile ologbe na lo si pese orisirisi nje ọun silẹ lati fise eto ariya na, Nigbati odi irọlẹ ọjọ ninu ti ọjọ Ajọdẹ ni - ẹmọ obirin ologbe na pelu baba ti Ademoyi Ọsọbu pe ogunlọgọ awọn enia si aungbo Anaye fun ariya oku na. Bi onikalu ku awọn enia wọn i ti nde ni agbe onjẹ aladun niwaju wọn, bi wọn si to njẹbun tan ni abere si yo ọti bu jade bi omi onikaluku awọn ti owa sibẹ lo jẹ to osi mun amuiseku ọti.

Awọn onilu adapọmọ igkere ati aro se kiki lọjọ na, bẹni ọgbẹni C A Balogun pẹlu awọn elere rẹ se bi bẹ lọjọ yen, onikaluku awọn ti owa sibẹ lo si nawo pupọ fun awọn onilu mejeji na.

Nigbati odi ọjọ Monday ni Ọgbẹni Agboye Makinwa ati awọn aburo rẹ se ariya ti wọn pelu, ogunlọgọ awọn enia pataki pataki losipe wa sibẹ ariya na.

Irawo ọjọ yi po pupọ ako le rohin rẹ tan afi enia oba lọ sibẹ awọn enia si sere inu mọju ọjọ keji pelu awọn ilu a adun, ati onjẹ pelu ọti itọhin ko ni afojubu ni irawo ọjọ yen jẹ.

Akọle oloto Ati ọgbẹni I. Agbọlu Makinwa, B B Makinwa, S O Makinwa, Ladunni Makinwa, Adebaye Makinwa, Adunọla Makinwa, Jos eph ọla Makinwa, Victoria Bosede Ademọla Ọsọbu ati awọn idile Makinwa toku pe eku irawo Oluwa Ọba yio fi enia rere gbehin yin laiye, Oluwa koni jẹki eri iku akuf ni idile yin. Aṣẹ.

## OTITỌ-NI-NTONI—NIPA ỌRỌ AWỌN „AGBERO"

(Lati ọwọ A E Fashugba, No 33 Iteja.)

Jọwọ gba mi laye diẹ, ninu iwe rẹ Oloyinmọmọ yi, lati fesi si aba ti ọgbẹni J.O Ọmọtayọ da, nipa wipe ki a da awọn agbero duro lẹnu iṣẹ na, nitori idi eyi to fi gbe wọn ba Ọlọpa, Ijoye ati Ọba ni ẹhin-enu. lati ri wipe ki a gba wọn si enia-kenia tabi ole ati adaluru, Ohun buburu ni eyi patapata.

Ninu awọn agbero wọnyi ti ọgbẹni Ọmọtayọ li nsun yi jẹ ọmọ Ọba, Ọmọ Ijoye ati Ọmọ bọkini ilu ti o ba jẹ wipe Ọgbẹni Ọmọtayọ ba urinkiri ni, yio ma gbọ ni gbogbo Teṣan reluwe pe awọn bi agbero wọnyi ni a npe ni "porters,,"

Ohun ti emi ro ti arakunrin yi ibawi nipa awọn agbero wọnyi nipe ki wọn tun eto ẹgbẹ wọn se, ki wọn si ripe ofin daradara wa larin wọn, ki wọn si mu ẹda ofin yi ranṣẹ si awọn ẹgbẹ onimoto, (Motor Owners) Union) ki wọn tun fi ẹda iwe yi kanna ranṣẹ si A'ẹle ati Ijọba Ijẹṣa un ifẹsẹmulẹ daindain.

Eniti oye ba yẹ dada yio mọ wipe iṣẹ agbero, iṣẹ oniranlọwọ ni fun onile ati alejo a le ri eniti onja ele ninu wọn lotọ, se anri awọn ọga Banki ti o njale, bẹna ti ni anri nire awọn Sarmen ilu tio njale bakanna. Ako le tori be le awọn ti ko njale wọnyi kuro lari ilu, ika ti o base si Ijọba nke.

Nwọn igbati ọga ile banki ati awọn tanmọri ilu ti wọn jale ti Ijọba si fi wọn si ẹwọn, wọn tun jade tan, ti wọn tun ri ise se, bi aba ti ele ninu awọn agbero, ti o ba pari iya ise re tan, yio tun bẹrẹ ise re ni.

Mo fẹ ki arakunrin mi yi mọpe iṣẹkiṣẹ ti enia ba nse lo ati onje ojọ se nibẹ Iṣẹ nise papa (Ede Oyinbo kan sope:-if you strile tis no disgrace.)

Laipe yi mo ri awọn agbero ti ngbero fun moto to nlo si ilu-Ose ti wọn tikalara wọn mu enikan ti efi ara lan bi enia kenia ati oni janduku wa si ti Ọlọpa fun ijẹniya nitoripe olu ọmọbuin kan laisidi, osi da oja ti ọmọbuin na nia nu, bi wọn ki ba se enia rere ni, wọn ko ni se eyini, wọn iba mu oju kuro ni, laisi agbero enia ko le tele si moto wọ leko.

Nitori a ṣ jẹ ka se otitọ nitori otitọ ni ntọni.

## AKIYESI

FUN GBOGBO ỌMỌ ẸGBẸ NCNC-ẸGBẸ AKUKỌ

Afẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ NCNC mọ pe ipade ọjọ mẹjọ-mẹjọ ti a nse ni Wednesday ko yi pada nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sokan lati ma wa si gbogbo ipade dede.

# E ma ka Irawọ Ọbọkun, ki e si ma p'olowo oja yin sinu re nitoripe tiyin ni.



QGBENI QLADIMEJI OSUNGBURE

On jẹ enikan pataki ninu awọn ẹgbẹ ọdọ ti Afẹnifẹre ti ọse ipade nla kan pataki ni aipẹ yi,ninu eyiti ogunlọgọ awọn asoju wa lati ọpọ ilu ni Iwọ Orun Nigeria

## QRQ LORI QNA AGBEGBE

Lati ọwọ Oselu S. A. Famuyide

Mo ki gbogbo ẹnyin ọmọ Obokun ti o wa ni ile, agbegbe ati ẹhin-odi. Mo si tun ki nyin pe ẹ ku orire, fun ti ọmọ nyin, Ọgbẹni Isaac Ajanaku ti awọn ẹlẹgbẹ rẹ, Action Group sẹsẹ roun kan lati yan ninu ọmọ Ijẹsa si ọkan ninu awọn aye giga ti o wa ni abẹ aje Ijọba Iwọ Orun.

Idi pataki ti mo fi ki ẹyin pe ẹ ku orire nipe awọn baba wa ma npa owe bayi pe "Apẹ jeun ki ije ibaje toto o se bi owe o. Ipo na se pataki tobẹ, ti o fi jẹ wipe Ọgbẹni Ajanaku je okan ninu awọn ọjọgbọn ti yio joko lati se eto lori pipin owo nlanla kan tise ẹgbẹgbẹrun pouṅ lọna ẹgbẹrun ni ọna mẹrin-di arin awọn gbogbo apiniẹ ti o wa ni Iwọ Orun lati fi tun awọn ọna ṣe ati lati fi da ọda si awọn ọna na.

AGBQSQ QRQ

Ọrọ nde oti bo ọpọlọpọ enia wipe Ọgbẹni Ajanaku ti ose ileri pe ọna meji pere ni on yio jeki o ri anfani ninu itẹsiwaju na sugbọn emi gẹgẹbi enikan, agbọsọ ọrọ ni mo gba si, eyiti mo ro pe o yẹ ki o jina si otitọ. Nitoripe emiti yio se ẹtọ ati eto dada ni emi mọ Ọgbẹni Ajanaku si, ati pe yio si lo ipo na lati fiban ọpọlọpọ miran ti ko mọ gẹgẹbi emi ti mọ si.

Mo si tun bẹ ẹnyin ẹlẹgbẹ mi oselu ti ẹ wa ni Committee ti o nboju to eto nipa awọn ọna ti o wa ni ẹkun Ijẹsa ati ilu Ilesa, o pe ki ẹ pe Ọgbẹni Ajanaku wa si ipade nyin lati jọ se ipade pọ ki ẹ si fi ẹsẹ rẹ le ọna dada ti yio ṣe gbogbo wa ni anfani.

Ọpọlọpọ ọna ni o wa ni agbegbe ati ilu Ilesa ti o nfẹ titun se bi apẹrẹ emi yio toka si ọkan ninu ọna agbegbe ati ọkan ni igboro ọna Enọni ati ọna ti o gba topopo Odo-Isida kọja.

Eyi ni eto ti a ti ṣe silẹ fun awọn ọna na lati odun ti o kọja.

Ijọba Ibile wa tiṣe awọn eto wonyi nipa imnilọwọ Ọgbẹni E. Kolawọle alabojuto iṣẹ ọna Ijọba wa ti Ijọba Ibilẹ ti palose pe ki o ṣe awọn eto wonyi lati gba owo lọwọ Ijọba fun awọn ọna ti [illegible] si itsalẹ wọnyi se ati lati da ọda si wọn.

Fun akiyesi awọn ọna bi meji tabi mẹta tun ni anfani miran lati ri owo lo ninu apo inawo ti, awọn eleto lori cocoa ati ekurọ ni Iwọ Orun.

(Bẹrẹ lọsẹ to nbọ)

E MA KA IRAWO OBOKUN

Nitoripe yio ma gba irohin igbimo ijoba yin jade nigbakugba.

A si tun fe asoju ti yio ma ko irohin ranse siwa lati akamo igbimo kokan

A ti fi aye sile fun irohin lati ibikibi ki awon olufe akamo kokan le ma ri irohin igbimo akamo ti won ka.

## ẸGBẸ QDQ ACTION GROUP ṢE IPADE

Lati okan bi ọsẹ meji sẹhin ni ẹgbẹ Action Group ti nfi ifilọ sode pe awọn yio ṣe ipade ajọdun ni Ilesa.

Bi o ti di owurọ kutu ọjọ Satide ni wọn lọ ta asia ẹgbẹ wọn siwaju Gbọngan Obokungbusi; O gba awọn alaṣẹ Gbọngan na ni asiko pupọ ki wọn to gbẹbẹ wọn pe ki wọn gbe asia wọn nilori pe agogo mẹsan alẹ di owurọ ọjọ keji ni aye ti wọn torọ rẹ fun.

Lati igbana ni wọn ti gbe moto ti wọn fi nṣe kund kunde ati moto ọlọpọn ti Ọgbẹni Kayanfada ti wọn joko leti rẹ yipo, ti Ọgbẹni C. A Balogun pẹlu awọn isọgbẹ rẹ nkọrin ninu moto kundekunde wọn. Bi wọn ti njo kiri ni awọn ọmọde nho tẹle wọn.

Ni ọwọ agogo mẹrin ọsan ni wọn dari si Banusọ. Nigbati o di nkan bi agogo mẹrin na ni wọn nforin pariwo niwaju Gbọngan Obokungbusi lati di awọn NCNC to nsọrọ nibẹ lọwọ

Ni nkan bi agogo marun, nigbati o ku diẹ ki NCNC kuro tan ni Obokungbusi ni aṣaju ẹgbẹ Action Group kan pẹlu Ọgbẹni Joshua Aromọlaran sọpe ki wọn ta asia wọn ṣugbọn awọn to wa nibẹ kọ.

Ibiti wọn ti nfa ọrọ mọra lọwọ ni ẹnikan ninu wọn sare lọ si Banusọ pipada to pada lo de pẹlu awọn ẹda bi jaguda mẹrin kan pẹlu koboko lọwọ. Bi wọn ti de ni wọn bẹrẹ si ibọ aṣọ ija silẹ. ọkan ninu wọn lọ nsọrọ abuku si Ọgbẹni Ogunbiyi ọkan ninu awọn amofin (Lawyers to jẹ ọmọ Ijẹsa.

Ogunbiyi ko sọrọ titi. Nikẹhin ti wọn lọ tan, lo kilọ fun awọn NCNC to wa nibẹ pe ki wọn kuro nibẹ kia, nitoripe awọn ẹgbọgi ọmọ Jaguda ti gbogbo Ibadan mọ ni Apẹlẹwọn ni gbogbo awọn to fẹ ja na. Lẹsẹkẹsẹ ni wọn kuro nibẹ fun wọn.

Nṣe niwọn pariwo di ọganjọ ninu Gbọngan na. ọpọlọpọ awọn ti wọn fi iwe pe lo sa pada nigbati wọn ri ogunlọgọ awọn Apẹlẹwọn bi ọbọ nibi ijo na.

Ni ọjọ Sunday, ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi ni Ọlọla Akintọla ba wọn sọrọ ni Gbọngan kanna Ohun to sọrọ le lori ju ni ọrọ Reluwe Akintọla. Odidi wakati mẹta lo fi sọrọ.

Bi Akintọla ti nbu Ọlọla Oluwole Komọlafẹ ninu ile bẹ ni awọn Apẹlẹwọn nfi koboko da bira ni ojude. Ogunlọgọ enia ni wọn na ni anaferẹku. Diẹ ninu awọn ti wọn na ni Ọgbẹni Ladiran, Eman Olowokere; S. Komọlafẹ, Jackson Tejere, to ngbe E128 Ita Ọgọ, ati S. Ade Ajayi to ngbe AT 53 Ogudu.

Nṣe ni Jackson Tejere sa wọ Afin Ọwa lọ, ọpọlọpọ awọn eto lo gba Ade Ajayi silẹ.

Ti o ba jẹ pe Ọgbẹni Ọmọregbe (Inspector of Police), ko si nibẹ ni, ija igboro iba bẹ silẹ Ọgbẹni Ọmọregbe ko wọ aṣọ ọba, ṣugbọn gbogbo agbara rẹ lo fi nla ọpọlọpọ ija.

Ẹṣẹ ti Ade Ajayi ṣe nipe o nlọ si Eko, o si fẹ lọ wọ moto ni Ita Balogun, o gbe adiẹ kan lọwọ; adiẹ na ni awọn pẹlẹwọn ri ti wọn sọpe awọn fẹ pa Akukọ. Ade Ajayi wa nile nisinyi, ko le lọ si Eko mọ.

Ohun to ya ni lẹnu nipe wọn ni ọga awọn ọlọpa Ijọba Ibilẹ, (N. A. Sergeant) sọpe kinise ti Ade Ajayi fi gbe adiẹ kọja nibẹ A si gbọ pe ọpọlọpọ awọn ọlọpa N.A. ni wọn na, ṣugbọn wọn ko le mu enikankan ninu awọn Apẹlẹwọn na.



KAN'ELQ J J IBIRONKẸ

On je ọkan pataki ninu awọn oṣiṣagbọngbo ti ẹgbẹ Alakukọ on na si wa pẹlu awọn ti o lọ si ibi ipade ti aṣe laipẹ yi ni Gbọngan nla Obokungbusi.



ỌMỌ'BA S A ADENIRAN

On na wa pelu ogavogo awọn enia pataki ti o lọ si ibi Ipade Ijọba titun ti agbe eco so kalẹ laipẹ yi

## IṢE ẸRANKO IṢE ỌMỌ ỌLỌPẸ

(Bẹrẹ loju iwe 5)

never the less I am in sympathy with any one that caters for a free and united Nigeria.

Ninu iwe to fọwọ si o leri pe "Emi yio sa gbogbo ipa mi lati ri pe mo se iwọn ti mo le se lati ripe ẹgbẹ na (N C N C) ni idagbasoke ati itẹsiwaju, lede Gẹsi o leri pe "I hereby also promise to do all that lies in my power that will contribute to the growth and progress of the party".

Loni, o han si gbogbo agbaiye pe o mu ileri na ṣẹ. Emi imore ti ẹgbẹ na fihan ni pe wọn iṣe igbakeji ẹgbẹ ala na.

Ninu iwe kẹta o sọ fun Ọgbẹni Iles pe emi yio duro ti NCNC". lede Gẹsi "I will support the NCNC".

Ṣebi ki ṣe on nikan lo fọwọ si iru iwe bẹ. Njẹ loni o faramọ NCNC tabi ko faramọ? Nibo ni ẹnikeji to fọwọ si iru iwe kanna faramọ loni?

Kọlọkọlọ lana. Opolọ loni, Donald Ade Arọyọ, ewo ni ẹ o jẹ lọla o.

### IJA AJAPA

Ni ọjọ kan, Ajapa lọ si oja, o ba ẹnikan forigbari lọhun, oni- tọhun si fi gbajumọ han. Oju ti Ajapa, o tẹsẹ mọ irin, o dide. Ajapa dele o bẹrẹ si ifi ikanra mọ ara ile.

Bẹ gẹgẹ ni ọrọ Ọgbẹni Joseph Falana to ni ile itaja ẹgbogi si Okeṣa Ilesa.

Ọmọ ẹgbẹ Opẹ ni Ọgbẹni Jo- seph Falana nṣe. O lẹ aworan Awolọwọ mọ ile, o sọ panu ọlọbọ mọ fila, gbogbo orin isinku Opẹ lo mọ kikọ. Ko si ẹniti o mọ iyatọ ninu on ati awọn Ẹlẹri Jehofa to ba ogbe kundekunde Opẹ kiri.

Ṣugbọn sibesibẹ, wọn yan Kansẹlọ ni Okeṣa wọn ko mu. O fi Okeṣa silẹ, o lọ si ilu rẹ ni Ọgọtun nibiti wọn ti mọ lati kekere. O ba awọn ọmọ Akukọ Ọgọtun forigbari nigbati o fẹ ṣe Kansẹlọ, ko jẹ

O ba fi itiju pada wa si ibi iṣe rẹ.

Ni ọjọ karundogun oṣu yi, awọn onisowo ọja fẹ dibo mu ẹnikan ti igbimọ ti iitun sọpe ki wọn yan ti yio ma ṣoju wọn ni Kọmiti kan. Ọgbẹni J. O. Mọtayọ forukọ silẹ pelu awọn meji miran pe ki wọn dibo fun on. Won dibo, ibo ko mu Mọtayọ. Wọn ni Ọgbẹni Joseph Falana wa dahun pe tori Ekiti to jẹ ni ko jẹ ki wọn dibo fun, lo wa bẹrẹ si isepe le Ijẹṣa lori.

Gbogbo ẹnyin ọmọ Ekiti to wa ni ilẹ Ekiti ati gbogbo ida le ẹ raiye lode tabi ẹ ko ti o? Falana fẹ ṣe Kansẹlọ ni Ọgọtun ilu rẹ, wọn ko mu, sugbọn J. O. Mọtayọ fẹ wọ Komiti ni Ilesa wọn ko mu Joseph Falana wa nsepe le Ijẹṣa lori Ṣe tori Ekiti ti on na jẹ ni wọn ko ṣe dibo fun ni Ọgọtun ilu rẹ?

Bi Ijapa ja lọja, to wa nda eru nile, eru na yio pada to o

Ra Irawo Obokun.

## OLUWA MA JẸ KI NFI OGUN BABA MI FUN Ọ

Lati ọwọ Ọmọba Gbadebo Bepo, ABEOKUTA

Olotu, Iwaju ni ẹn ma lọ. Ali- bojuto Olotu a ko ni di ẹru ẹlẹ- lagbara Edumare, atubotan ajince aiye, iwe irohin ti Pangadi yio sẹhin wa ba wa, pelu ore ọfẹ ti Oluwa. Ọmọ Kiniun ni, Judah ọmọ mi, ọpa alade ki yio lọwọ rẹ kuro: Genesis Ori 49, ẹ 10

Awa dupẹ ẹjọ o, Baba wa Oduduwa Ọwa Adimula ti gba gbogbo ilu Ijẹṣa, ẹ ku ori rere na, ori ti o ba Ade na jọ, ẹ ku ajoyọ, Baba ati Iya wa gbogbo ti nu Ẹsa-Oke Ijẹṣa, papa awọn ara ilu Ẹsa-Oke ẹ jẹ ka fi ọrọ laisi ibinu, tabi ẹgan ara wa wo ẹsẹ 10 iwe na daradara, ... wipe oye lọja Ẹsa Oke jẹ oye bi Ọba lori gbogbo ọmọ Ijẹṣa, ile oye rẹ kan wa ni ilu Ẹsa-Oke ni oye wọkun wọsa ni. Nitori idi eyi o ko le da igbo ... lẹhin onigbo, Ọba Agunbiade II, Ọba Arojoye II, Ọba Awogbọrọ II, Ọni Ifẹ-wara ati awọn Lọja bi Lọja Ibode, Ọba Imẹsi Ijẹṣa.

Awọn Ọba ati Ijọjalọjo bẹ wọn ki ṣe Ọba tabi alaṣe ilu Ijẹṣa ti ile oye wọn wa bikoṣe Ọba ati alaṣẹ lori gbogbo ọmọ Ijẹṣa ti ile ati awọn to wa ni idalẹ, Oluwa yio mu wa lọwọ oju ko ni ... agẹẹbi agbo kan labẹ olori olu- ọ agutan kan ni gbogbo ile Ijẹṣa

Awa bi Ijẹṣa ni orukọ ati okiki ọla ati ola wa nga bi oke Imọ ni gbogbo aiye loni yi, Ẹ jọwọ ẹ maṣe jẹki a fi iwa ọtẹ ba ohun ti a ni ṣe jẹ o, gbogbo wa papọ ni ọmọ Obokun.

Nitorina mo fi iwe yi bẹ gbogbo gbogbo ọmọ Ijẹṣa ... ẹnikan iba ṣe A. G. Ẹgbẹ Afenifẹre tabi NCNC ka ronu wo ka tun ero ara wa pa, ka pa iwa ọtẹ ..., ka ni adura apapọ lati ọdọ Olọrun wa ki Olorun maṣe jẹki ori ... ẹdẹ wa daru mọwa lọwọ, lọ jọ ti oniyi.

Ijọba Ibile ti a le fiwe Ijọba Ibile Abẹokuta ko ti si ni, sibẹ ohun to kele niwọn abẹrẹ ti ẹ le bere ti a ko le sọ nipa rẹ ko woro ni ilu Ẹgba. Alagba Baba wa J. F. Longe, Olori Ẹgbẹ Atunluṣe ẹ dide si o, nitori ọrọ Ijẹṣa ... ẹtẹ ni, ati mo eyi ni ... kato di oni ise oye ti Olorun ti fi e jẹ. ma fẹ yoju o, ma ... Ijẹṣa eikan kọ ni o jẹ oye yi fun ọ, ti apapọ gbogbo ... ni aye yin jẹ o.

Ṣe ... Ọlọla Sadauna ti ilẹ Sekoto ... o, ẹnu agba ni obi gbo ... o, ... ara yio ma jẹ o Baba wa ọmọ Obokun, njẹ ẹ ko gbo ọrọ awuri ti Ọba Alayeluwa ... ti ilu Oṣogbo sọ ni ọjọ ... ile Alagba Ọlọmọyindoyindo ni ilu Oṣogbo, Kabiyesi Adimula, Kiniun Judah.

Nigbati mo aworan ida na ti Ọba ilu Oṣogbo ... ṣe atẹgun nipa ... ati aworan kiniun ati ... irawọ to ti imọlẹ rẹ kan si gbogbo wa bi Ijẹṣa wipe ... irawọ owurọ lo ṣe amọna fun awọn amoye ti ijọ kini. Inu mi dun si wipe Ọlọrun ... lo oye amọna Ijẹṣa, ni agbara ti Oluwa a ko ni ṣina ... Inu mi dun lati kọ orin yi pe, Emi yio fi Ilẹ a ṣe oṣo, ilẹ ominira, lori oke ati petẹlẹ, ... agbe tomi dagba o emi ọmọ Obokun.

Mo tọrọ gafara lọwọ baba wa J. F. Longe lati fi ọrọ kekere yi ranṣẹ si ẹgbẹ Atunluṣe ti ilẹ Ijẹṣa, ... gbigbẹ, ti ohun ti afata nko o, Agboku aiye ẹni jijẹ, ... Ọrọ ti Sobọ-



ALHAJI A. R A. SMITH

O jẹ Ogunagbenjbo ninu ẹgbẹ Afenifẹre A. G. On na ti ba awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ lọ si Obokunghusi lati lọ ... igbekalẹ Ijọba titun.

## IDDO PROGRESSIVE UNION ṢE IPADE

Diẹ ninu awọn ọmọ Iddo Progressive Union-Ẹka ti Ileṣa lọ si Iwarọ ni 3-4-55.

Ni ile Loja Iwarọ, lọdọ ọgbeni Joseph Ogunmoroti ni wọn ti se ipade.

Ki ipade to bẹrẹ, Oniwarọ fun wọn ni ohun ipanu diẹ ati ohun mimu pelu.

Wọn bẹrẹ ipade na labẹ iṣalaga ti Ọgbẹni, Joseph Ogunmoroti Ẹniti o se adura ni Ọgbẹni D A. Apata.

Ni dede agogo mejila ni awọn aṣoju Ipade Ekiti Parapọ ẹka ti Oṣu de.

Lẹhin igbati wọn ti fi ara wọn han ara won ni Ọgbẹni na fi iyan, rice, ẹmu ọti, siga ati obi lẹ wọn lọrun.

Wọn jẹ, wọn mu ti ti di agogo merin ti wọn pari ipade na pelu adura.

Awọn enia pataki ti o wa si ipade na ni: Oniwarọ J F. Fawekun (Alaga) Ade Agbo Akilo Akọwe), E. I. Olatunji (Asoju,) (F. Faṣoshe, Ọmọlade Adeyẹmi, D. A. Aseta Wuraọla Balogun, S. B Ogun Vasco (Akapo) E. P. U Oshu) M. Ade. Ojo Tailori Akọwe E P U (Oshu) ati Bricklar Igbakeji akapo.

## OLUWA MAJẸKI NFI OGUN BABA MI TỌRẸ

(Bẹrẹ ni oju iwe 6)

aro bi odu, o ni atita owe, amayan ọrọ laya.

Koyẹ karo wipe Nitori Ọwa ti gbogbo Ijẹshe ngbe igboro Ileṣa nisisiyi nitori na awọn to ngbe igboro Ileṣa nikan loni Ọwa. Ẹ jẹ karanti pe Ọwa ti gbe, ilu bi, Igbadae, Ibokun, Ilọwa, Oke-Osin Ipole, Iwori at Ẹjiọrọ ni ki wọn to wa fi Ileṣa se ilu ỌbaỌwa

Nitori idi eyi o yẹ fun wa lakoko yi lati ni irẹpọ ati ifẹ larin ara wa bi orilẹ ede kan na, iaisi ẹgan ti ilu, ti abule, ti ileto, ti ede ati ti isin, to bẹ ki iwa ati ise wa yio fi yẹ lati jẹ aworan ati aperẹ ifarawe fun awọn Orilẹede miran gbogbo to yi wa ka. Kasi ni ofin ti ibilẹ wa bi Ijesha ti ko ni fun ilu kan laye lati gberaga si Ọwa ati gbogbo awọn alasẹ ilẹ Ijẹṣa, mo si lero wipe iru ofin bẹ kise ẹsẹ si ara wa biko se lati fi ọkan alafia ilu wa balẹ, labẹ akoso awọn oni wa, ada ija silẹ taketo enia, Iru ofin bẹ wa ninu Ijọba ibilẹ si ẹgba, ti ofi ibẹru ọkan siwaju ẹnikan lati ma se tapa si egun Oluwa yio bawa se ti wa na si ọna rere.

Mosi nigbagbọ ni ọkan mi si Ọgbẹni S. A Faseyi ati J. Akin, Babajido, awọn sanmọri ọmọ Obokun to wa se asoju fun ẹgbẹ ọmọ ilu Ẹsa Ijẹṣa ti ilu Eko ni ọjọ 23 oṣu March, ọdun 1944, The Lagos C uncil of Ijesha Societis to The Alaiyeluwa The Ọwa of Ijesa Land, Ileṣa Mo ni igbagbọ si ifẹ wọn lakoko yipe Itan ẹran ati wa alafia ilẹ Ijesha pupọ ni awọn olufẹ ilu wa na yio fẹ lati ya fun ati gbe, Ọlọrun koni jẹ ka pa ofo o.

Ẹ ma se jẹ ka Ẹma yẹ eniti o, fẹ da otẹ silẹ larin wa si. Ka ma se jẹ ki wọn fi ọgbọn ẹtan fi wa se ọja tita larin ara wa si ara wa, kani ẹmi Ibu ọwọ fun ọba wa ati awọn alasẹ wa ni ilẹ wa bi Ijesha, Bi enie ba pọ ni ilẹ na, tẹni ni ẹni nkesi o, Tani isubu ati ẹtẹ orilẹ Ijesha wu? kamari ni Ẹgbẹ Ijeṣa Abẹokuta wo, Ọlọrun ọba edumare ko ni se ọba wa ati awọn ọba wa ni lẹ Ijeṣa ni ọba ti ao ma le kuro lori itẹ ọla ati ogo Ilẹ Ijẹṣa, amin aṣẹ, on ti Kesari ka fun Kesari e ohun ti Oluwa ka si fun Oluwa, mo da laba lati yan ikọ alafia fun ipari ede aiye na kiakia larin ara wa, yio yẹ wa o. Ni iduro iwe yi ka yẹ ọrọ yi wo bi ọmọ Obokun, gbe aiye rẹ ta ki o fi ere ti Ọrun kio le jẹ ere iye ainipẹkun.



ỌGBẸNI S. A. FAFOWORA

On jẹ ọkan ninu awọn ọjanigbọnṣọ ninu ẹgbẹ Afẹnifẹre on pelu awọn ti ọ ba asoju ẹgbẹ wọn lọ si Ipade



ỌGBẸNI E. A. EKUNṢEITAN

On ni Baba Ẹgbẹ Alakukọ ti Ileṣa on na si pelu awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ nibi eto ipade Ijọba titun ti agbe kalẹ laipẹ yi.


## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu "IRAWO OBOKUN"

### OJU EWE KINI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 8s. | fun inṣi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | " " " |
| Igba | 26—52 | 7s. | " " " |

### OJU EWE KEJI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 5s | fun inṣi kan |
| Igba | 13—25 | 4s. 6d. | " " " |
| Igba | 26—52 | 4s. | " " " |

### OJU EWE KẸTA

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 7s. 6d. | fun insi kan |
| Igba | 13—25 | 7s. " | " " |
| Igba | 26—52 | 6s. 6d. | " " " |

### OJU EWE KẸJỌ

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 6s. | fun insi.kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | " " " |
| Igba | 26—52 | 5s. | " " " |

OJU EWE 4, 5, 6, Ti 7 JẸ OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE KEJI.



OLOGBE J. M. MAKINWA

On ni ẹniti awọn ọmọ ati ebi ṣe ariya oku re ni ọjọ kẹsan ati ọjọ kewa oṣu yi ogunlọgọ awọn enia pataki losi wa sibi ar ya na lati awọn ọpọ ilu

# E KA NIPA IJOBA YIN

Laipẹ yi, ilẹ Ijẹsa yio di ọkan ninu awọn ipinlẹ ti o ni ijọba alajumọ-ṣepọ n pa nini igbimọ iṣejọba mejilelogun.

Wọn ni "bi egungun ẹni ba njo daradara, ori ẹni a ma ya" Irawọ Obokun lero wipe yio jẹ idunnu olukuluku lati ma ri irohin itẹsiwaju ka nipa igbimọ-ijọba akamọ tirẹ; nitoribẹ, a ti nṣe orisirisi atunṣe ni imurasilẹ lati ma ripe irohin njade ni ọsọsẹ nipa gbogbo awọn ijọba na.

Inu wa yio dun bi ẹnyin ọkawe wa ati aṣoju wa ba fọwọsowọpọ pẹlu wa lati ripe iṣẹ na rọrun ni ṣiṣe

Ọna ti ẹ fi le ran wa lọwọ nipe:-

A fẹ Aṣoju (Agent) ni ilu kọkan.
A fẹ aṣoju si ni Ileṣa.

A fẹ awọn ti yio ma fun wa ni irohin pipe.
A fẹ awọn Ọkawe kun awọn Ọkawe wa.
A fẹ ki awọn ti o mura tan lati ma ba wa ṣowo jẹ awọn ti yio ma sanwo lasiko.

Eto bi olukuluku ṣe le ma ra tabi ma ta iwe wa wa ni isalẹ iwe yi.

| | | | |
|---|---|---|---|
| Deposit | 10 to 50 Copies | -- | 10/- |
| | 50 to 100 ,, | -- | 20/ |
| | 100 to 200 ,, | -- | 41/- |
| Commission:- | 10 to 100 copies | 20o/o (4/- in £1) | |
| | 100 to 1000 ,, | 25o/o (5/- in £1) | |
| From 1000 upwards | Special arrangement. | | |

All payments should be made during 1st week in the following month, latest 2nd week after which supply would be cut off without notice.

Deposit could be withdrawn after a month's notice should in case the Agent does not owe any arrears if he or she wishes to discontinue the Agency.

# E ka Irawo Obokun




AWORAN IRAWỌ OBOKUN

Iwe Irawọ Obokun jade fun atunṣe ilẹ Ijẹṣa osi nran onikakulu awọn oṣelu titun lati ja ija rere fun igbega ilẹ Obokun laisi ọtẹ orikunkun, Abẹtẹlẹ, Ẹgan Riba ati iwa buburu miran ti o le ba ilu jẹ. Tori na Ida Ajase ti o wa ninu aworan yi nle awọn ẹda abalujẹ lọ.

## ILU AMUYE KO FI ARA MỌ IJỌBA ILUPEJU

(Lati Ọwọ Oṣelu Ọmọba G. A Aromọlorẹ)

Ọlọtu jọwọ gbami laye lati ja irọ awọn alakuko ti o wipe ara Amuye bi u kuro ninu igbimọ Ijọba Ilupeju ninu iwe rẹ oloyin mọmọ yi:

Ọrọ na ti oju su mi nigbati mo ri ka ninu Irawọ Obokun wipe awọn ilu Amuye binu jade ninu Igbimọ ijọba Ilupeju eyi ti o jẹ wipe ẹnikankan ko lọ ninu Ijoye tabi Kanṣelọ kan ni ilu Amuye

Ẹjọwọ mo bẹ ẹyin ọmọ Obokun ki ẹ ma ọ Irawọ Obokun wa yi di Irawọ Irọ o ohun ti oju wa ba ri ni o ki a ma sọ. Obokun ngbe yino. Mo si fẹ ki o da yin loju wipe nwọn ko ni lọwọ ninu igbimọ Ilupeju na. Nitoripe ẹnikan kan ko mọ igbati nwọn sọ Igbimọ na ni Ilupeju rara bẹni ara ilu Amuye ko si lọwọ ni eto wọn.

Printed and Published by Ijesha Press Ltd., B110 & B149 Okesha Street, Ilesha 25 - 4 - 55